# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, ITENI OBOGBO LAWA

No. 749 TUESDAY, JULY 21, 1564 (2D)


## Taylor Şe Ibẹwo Ile Ejọ Ilu Eko

EKO:— Laipẹ yi ni Olori adajọ ilu Eko, Ọgbẹni Joseph Idowu Tayler ẹni to ṣẹṣẹ de ipo Olori awọn adajọ ilu Eko laipẹ yi ṣe ibẹwo si awọn ile kekere to wa ni ilu Eko

Ọgbẹni Joseph Taylor ṣe abẹwọ ile ẹjọ kekere to wa ni adugbo Igbeṣere L'Eko ninu awọn to gba laṭẹjọ ni ọjọ na ni Ọgbẹni William Akibo Savege adajọ ni ile ẹjọ na ati awọn Ọga ninu awọn oṣiṣẹ to oṣiṣẹ ni ile ẹjọ na.

Ninu awọn ibi ti Ọgbẹni Joseph Idowu Taylor ṣe ibẹwo rẹ ni ile ẹjọ na ni ile itọ, ati ile iyagbẹ, ile ẹjọ kekere ti nwọn nti awọn ọdaran mọ ni ile ẹjọ na ati ibi iṣẹ ti awọn Ọlọpa to mu ẹjọ awọn ọdaran wa si ile ẹjọ nibi ti nwọn yio joko si ki adajọ to ṣe ẹjọ ọdaran ti nwọn mu wa si ile ẹjọ na.

Ọpọlọpọ nkan ni awọn Ọga ninu awọn oṣiṣẹ ni ile ẹjọ giga to ba Olori adajọ na wa ṣe ibẹwo ile ẹjọ na si kọ silẹ ninu ile ẹjọ ti Ọgbẹni Taylor ṣe ibẹwo rẹ ni ọjọ na.

# EGBE N.C.N.C. FẸ ṢE ÌWADI OLOYE BENSON

BENIN:- Ninu ipade ti awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ṣe ni ilu Benin ni ọjọ Isegun ti ise ọjọ kọkadinlogun oṣu yi ni irohin ti de eti gbọ wa pe awọn ọmọ ẹgbẹ na ti yan awọn igbimọ kan lati ṣe iwadi akitiyan Alakoso eto irohin fun apapọ Ijọba Niajiria, Oloye T. O. S. Benson.

Bi nkan bi oṣu melo ṣẹhin ni awọn ẹlẹgbẹ Oloye Benson ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ti nfi pasan ọrọ na Oloye Benson lori iwa rẹ ninu ẹgbẹ na.

Oloye Benson ko ba awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ lọ sibi ipade ti awọn ẹgbẹ na ṣe ni ilu Bennin ni ọjọ Isegun nitoripe oloye Benson ko si ni ile yi. Oloye Benson si lọ fun ipade kan ni ilu Cairo eyi ti awọn Alakoso ilẹ enia dudu lọ ṣe laipẹ yi eyiti nwọn nse lọwọ bayi.

### IKILỌ

Ninu ipade ti awọn ọmọ ẹgbẹ na ṣe ni ilu Benin eyi ti olori ẹgbẹ na ati Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ila Orun jẹ alaga rẹ ni irohin na tun ye wa pe olori ẹgbẹ na se ikilọ fun awọn ọmọ ẹgbẹ na pe ko gbọdọ si ninu awọn ọmọ ẹgbẹ na ko gbọdọ tun ba awọn oniwe irohin se ipade kan ti ti awọn igbimọ oluwadi na ba fi ṣe ise wọn tan lori iwadi ak ti yan oloye Benson ninu ẹgbẹ Alakukọ ti nwọn si gbọ esi abajade iwadi na.

Ni kutukutu ọjọ ti awọn ọmọ ẹgbẹ na yio se ipade wọn ni Olori ẹgbẹ na Dokita Michael Okpara ti dẹ pẹlu awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ ti nwọn to iṣẹ Benin. Iyawo Olori ẹgbẹ Alakukọ Iyaafin Adamu Okpara si ba ọkọ rẹ wa sibi ipade na.

Ọpọlọpọ ẹyẹ ni awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ni ilu Asaba ati Agbor ṣe fun Dokita Okpara nigbati o fi gba awọn ilu na de ilu Benin

Oloye Festus Okotie-Eboh Alakoso eto iṣuna fun Apapọ Ijọba si tete de si ilu Benin ki ipade ẹgbẹ Alakukọ to bẹrẹ ni ọjọ na.



DỌKITA M. I. OKPARA

Ninu awọn enia to lọ pade Oloye Festus Okotie-Eboh lẹsẹkẹsẹ ti o de si ilu Benin fun ipade na ni Oloye Humphrey Omo-Osagie Alakoso eto Ijọba Ibilẹ ati eto oye fun Ijọba Agbedemeji Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria, Dokita Christopher Okojie ati Ọgbẹni Webber Egbe pelu ọpọlọpọ awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ. Oloye Okottie-Eboh ba awọn ọmọ ẹgbẹ na ṣe ipade aṣiri kan ni ile isimi ti (M and K).

Nigbati awọn Oniwe irohin bere lọwọ Oloye Okotie-Eboh pe kini ọrọ ti o ba awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ sọ? Oloye Okotie-Eboh si dahun pe ki awọn oniwe irohin fi on silẹ ati pe on ṣe ọjọ ibi on.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na si ṣe ipade eyiti nwọn wa ṣe ni ilu Benin ni ọjọ na ni ile isimi ile iṣẹ eto idagbasoke ti Ijọba Agbedemeji Ipinlẹ Iwọ Orun Naij'ria.



Oloye T. O. S. BENSON

Irohin tun fi ye wa pe ninu ipade ti awọn ọmọ ẹgbẹ na ṣe ni ọjọ na pe wọn fun Olori ẹgbẹ Alakukọ ati Alakoso Ijọba Ipinle Ila Orun Dokita M. I. Okpara ni abajade si Igbimọ oluwadi ti Oẹ'zu ti o ṣe iwadi lori awọn enia kan ti awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ sọ pe nwọn fi dite si Ijọba Ipinlẹ Agbedemeji Iwọ Orun Naijiria eyiti ẹgbẹ Alakukọ nṣe Akoso rẹ Dokita M. I. Okpara yio lọ ka eto abayọri esi Oluwadi na dada fun igba diẹ.

Oniwe irohin wa to wa nibi ipade na ni Benin fi ye wa awọn ọmọ ẹgbẹ Alakoso si tun ṣe ayẹwo lori ajumọṣepọ ẹgbẹ Alakukọ ati ẹgbẹ Afẹnifẹre ati awọn eto ye ki awọn ọmọ ẹgbẹ na yio ṣe lori ajumọṣepọ nwọn lasiko idibo si ile igbimọ asofin ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria.

Oniwe irohin wa tun fi ye wa pe nigbati on bere lọwọ ọkan ninu awọn olori ẹgbẹ na to wa sibi ipade pe kini ẹrọ ẹgbẹ wọn pelu

WO OJU EWE KẸFA

# Ekun Rẹrẹ Idajọ Oloye Awolọwọ (Apa 7)

Lẹhin ti Ibrahim Imam jẹri tirẹ tan ni Patrick Dokotri jẹri niwaju adajọ ile ẹjọ na pe ni ọjọ kọkandinlogun oṣu kejila ọdun 1962 ni awọn ẹlẹri fun Ijọba, Henry Oleari ati Anthony Oboh tun sẹ ni ile ẹjọ pe gẹgẹbi aye ipo ẹkọ ti awọn ọkunrin na lọ fun ati gẹgẹbi iranlọwọ ọga awọn ologun kan lati ilẹ Russia ṣe fun wọn ni ibi ti nwọn ti lọ fun ẹkọ iṣẹ ogun gẹgẹbi nwọn le ṣe doju Ijọba Naijiria delẹ ni Ghana.

Ni ọjọ kẹrinla oṣu kini ọdun 1963 ni ile ẹjọ na ọpọ lọpọ awọn ọlọpa ti nwọn mura fun ija tabi ti awọn enia kan fẹ da rediyan silẹ ni ile ẹjọ na lo si duro gbọni gbọnin, Iru awọn ọlọpa be meji si duro gbọin gbonin lẹhin awọn odaren na ni ile ẹjọ na.

Ni ọjọ kọkanlelọgbọn oṣu kini ọdun 1963 ọkan ninu awọn ọga awọn ọmọ ogun si tun se alaye nipa awọn ohun oṣe ti nwọn ri ko de on ko r pe awọn ohun oṣẹ na si tọ eyi ti awọn ọdaran na le fi ja ni nileigbimọ asofin ti Apapọ Ijọba, ọga ologun na si tun sọ pe ki ise iru awọn ohun ti awọn ọmọ ogun nlo ni eyi ati pe awọn ọdaran na le fi ba ile ati awọn ile miran to jẹ pataki jẹ.

Ni ọjọ kẹrinla oṣu kejiọdun 1963 ni awọn agbẹjọro fun awọn Ọdaran na si bẹrẹ si rojọ ni ile ẹjọ ni pe awọn Ọdaran na ko ni ẹjọ lati jẹ eyi ti Oloye Awolọwọ to gbẹnusọ fun ara rẹ tun fi nye ile ẹjọ pe Agbẹjoro fun Ijọba si ti fihan pe on ko ni ẹjọ lati jẹ niwaju ile ẹjọ na Oloye Awolọwọ tun sọ pe on si tun sọ pe on si nbọ lati di Alakoso ilẹ Naijiria laipẹ.

## ILE ẸJỌ DA ENIA MẸRIN SILẸ

Ninu awọn ti Ijọba ilẹ Naijiria ba nṣe ẹjọ iditẹ si Ijọba Apapọ ati igbogun ti Oba'binrin Gẹẹsi ni ile ẹjọ da awọn enia mẹrin ninu awọn Ọdaran na silẹ awọn ni Dokita Chike Obi, Olori ẹgbẹ Dynamic Party, Ọgbẹni Alfred Rewane, Akọwe Awolọwọ nipa ọrọ oṣelu, Ọgbẹni Tunde Amuwo, ati Muri Badmus.

Agbẹnuso fun ile ẹjọ na Ọgbẹni B. Kazeem fi ye ile ẹjọ pe ohun to fa ti nwọn le fi da awọn enia na silẹ nipe Agbẹjọro fun Ijọba ko ri ẹsun kan fi kan awọn enia na ati pe awọn enia to yẹ ki nwọn jẹri nipa awọn enia na ko si ni agbegbe.

Lẹhin ti Ọgbẹni B. Kazeem pari ọrọ rẹ lori awọn mẹta ni adajọ ile ẹjọ na sọ pe agbẹjọro fun Ijọba k tẹ on l'ọrun nipa ẹsun ti ile ẹjọ na fi kan Dọkita Chike Obi gẹgẹbi on ṣe ro tẹlẹ ati pe ki ise ẹsun to tọ fi kan Dokita Chike Obi Adajọ ile ẹjọ na sọ pe nṣelo yẹ ki nwọn fi ẹsun to yatọ miran fi kan Dokita Chike Obi, Adajọ na si sọ ni ikẹhin pe nitori na on da Dokita Chike Obi silẹ.

Ni ọjọ kẹjọ oṣu kẹta ọdun 1963 adajọ ile ẹjọ na tu ẹjọ ti awọn agbẹjọ pe si ile ẹjọ na awọn ọdaran na ko ko ni ẹjọ lati jẹ niwaju adajọ na. Awọn agbẹjọro fun awọn Ọdaran na tun bẹbẹ pe ki ile ẹjọ na gba iduro awọn ọdaran na ṣugbọn adajọ ile ẹjọ na kọ ẹbẹ iduro awọn ọdaran na silẹ Lẹhin na ni awọn enia mẹjọ ninu awọn ọdaran na sọ pe awọn ko ni sọrọ kankan fun ile ẹjọ na awọn enia na ni Gabby Shagọrẹ, Sunbọ Jibowu, Adeyiga Akinsanya, Joshua Akamọ, Samuel Onitiri, Samuel Otuṣarjọ, James Umore ati Uzodinma Nwobala.

Ni ọjọ keji oṣu kerin ọdun 1963 oloye Awolọwọ ti o gbẹnusọ fun ara rẹ bẹrẹ lati ma rojọ fun awijare tirẹ eyiti o pari ọrọ na ni ọjọ kẹtadinlogun oṣu kẹrin ọdun 1963 oloye Awolọwọ si fi ye ile ẹjọ de Igbimo

WO OJU EWE KARUN



OLOYE ỌBAFẸMI AWOLỌWỌ

# IWE SI OLOTU

## Ilu Omupo Nfẹ Ina Elentiriki

Olotu inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi aye die ninu iwe nyin lati kesi Ijọba Ipinlẹ Ariwa ile Naijiria lati fun Ilu Omupo ni ina Elentriki fuu ilosiwaju ati idagbasoke ilu wa.

Inu awa ọmọ ilu Omupo yio dun bi Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa Ọlọla Ahmadu Bello ba le lo ipo rẹ rere ki o tete da wa lohun fun nkan ti a nbere yi.

Awa ọmọ ilu Omupo ki i fi owo ori wa jafara lẹsẹkẹsẹ ni a si t te nsan owo ori wa a si fẹ ki a jẹ anfani owo ori wa ki a mọ ibiti a nna owo na si. Ọpọlọpọ nkan miran ni ilu wa si nfẹ sugbọn inu wa yio dun bi Ijọba Ipinlẹ Ariwa ba le tete da wa lohun fun awọn nkan ti a bere yi A o si ma reti nyin o.

Mo dupẹ pupọ o Olotu ajinde yio ma jẹ o.

Emi ni,
Emmanuel Alẹshinlọyẹ,
OMUPO

## E Jẹki A Bẹru Ọlọrun

Inu mi yio dun bi olotu iwe irohin Imọlẹ ba le gba mi ni aye die ninu iwe rẹ oloyinmọmọ lati kesi awọn enia wipe ki nwọn ni ibẹru Ọlọrun Ọba to da wọn

Idi eyiti mo fi nsọ ọrọ yi ni pe awọn enia kan wa ti nwọn nhu iwa buburu ti awọn enia ,na nhu eyi ti ko ba ofin Ọlọrun Ọba to da wa mu.

Iwa ki afi agbara ma mu enia sẹ awọn nkan ti ko fẹ eyi ti a nigbọ pe olodi sofi Ijọba to si jẹ pe awọn to ni Ijọba na lo nṣe okan na.

Enyin oṣelu wa yi ẹ jọ ki a ranti ọba Nebukadinessari ti o sọ pe ko si Ọlọrun kan Emyin ẹgbẹ oṣelu nwọnyi ẹ mọ nkan to sẹlẹ si ni ikẹhin nitori eyi mo bẹ nyin ẹ jẹ ki a ni ibẹru Ọlọrun ki ẹ ye fi pa mu enia ṣe chun ti ko fẹ.

Mo dupẹ pupọ Olotu.

Emi ni
Bode Thomas Awẹda
OMUPO





Our tradition is based on principles of lasting validity. Quality in every detail, true craftsmanship applied to most advanced production methods, safety and elegant styling. The scrupulous application of these principles in the design and manufacture of all Mercedes-Benz products is manifest in the product's performance and beauty. Mercedes-Benz vehicles of today are the embodiment of a 75-year tradition of progressive development in every sphere of car design and production.



MERCEDES-BENZ

DON'T FORGET THAT YOU CAN ALSO TRADE IN YOUR OLD MERCEDES-BENZ OR RENAULT CAR!

LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN, KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT-HARCOURT & ABA.

# Adura Egbẹ Ọṣelu Afẹnifẹre

Lati Ọwọ E. ALẸSHINLOYẸ

Ki Ijọba egbẹ Afẹnifẹre tete de
Aṣẹ tirẹ ni ka ṣe ninu iṣelu
Fun Ilọsiwaju ilẹ Naijiria
Ṣi ilẹkun ile owo nitori ọjọ aiyọ wa

Dari ẹṣẹ ji awọn ọd lẹ wọnyi
Nitori ọkẹ aimoye awọn Talaka
Ma fi wa silẹ fun Idajọ awọn alaiṣotitọ
Gba wa kuro lọwọ airijẹ ati airimu
Nitori dagbasoke Iṣẹ ni ilẹ wa
Emi Ilera ni tirẹ
Ogo ọmọ Yoruba tirẹ ni ṣe Titi lailai Amin.



OLOYE AWOLOWO

Baba wa 'rẹmi ti nwọn gbe s'ọgba ẹwọn
Kafi ogo fun oruko rẹ Mimọ

# Yẹ Irawo Re Wo

**AQUARIUS** (Jan 22 - Feb 20) Maṣe jina si awọn ara rẹ nitoripe awọn ko wa wo ọ, bẹni kiṣe ẹjọ ẹnikan, Maṣe jẹki iuu bi ọ koja ala lati oni lọ maṣe gbagbe iru ifẹ ti o ni si awọn enia nigba atijọ.

**PISCES** (Feb 21 - Mar 20) Bi awọn ọrẹ rẹ ba ki ọ loni, ki o yara da wọn lohun, ki o si yanju iṣẹ kan ti o ti wa nlẹ ti o ni lati ṣe.

**ARIES** (Mar 21 - Apl) Tọju amodi rẹ, ki o maṣe pada ṣẹhin ki oju re ma ba ri nkan ti ọkan rẹ ko fẹ, jẹki ori rẹ pe.

**TAWRUṢ** (Apl 21 - May 20) Yipada, ki o si tun iwa rẹ ṣe. maṣe rope nitu ọti mimu ni iwọ yio ti ri alafia, nitori ewu ikn omi rọ dẹdẹ lori rẹ, ṣora maṣe lọ si eti omi ti ojin, maṣe wọ ọko igi.

**GEMINI** May 21 - June 21) Ṣọra ki ijọngbọn ma ṣe bẹ silẹ larin iwọ ati ọrẹ rẹ, o si tọ ki o lo ọgbọn ori rẹ nipa ọrọ na, ṣe suru, ki o si wo ọrọ aṣiri kan yio ba ẹhin yọ si ọ lojiji.

**GANCEK** (June 22 - 23) Ṣọra nipa awọn ajẹni-ẹenia, nitori pe ọkan rẹ ko ṣekan, tun ara rẹ ṣe nipa eyiyi, nitori ẹ o fi egbogi ba ara nyin ṣe nkan ṣoro nipa ọrọ ti o njade lẹnu re, mọ ohun ti o nsọ.

**LEO** (July 24 - Aug 22) Maṣe ba ẹnikan ja, inure le gbe ọ koja ibiti o fẹde, ṣora ki awọn onijibiti maṣe ta jamba fun ọ, Maṣe ṣere kọja ala.

**VIRGO** (Aug 23 - Sept 23) Awọn obiorin yio ma nifẹ rẹ loni ọrẹ rẹ kan ti o ti nija pẹlu rẹ yio ba ọ pari ija ire si nb lẹhi rẹ.

**LIBRA** (Sept 24 – Oct 23) Alijannu rẹ yio kapa rẹ ati gbogbo adugbo rẹ pẹlu nigbati alijannu ba fi ọ silẹ nigbana ni ire de si ọ, oju ọna yiya dara fun ọ lati ma ya aworan.

**SCORPIO** (Oct 24 - Nov 22) Itẹlọrun yio wa ninu ile rẹ, ko ni si edekoyede ibaṣpọ iwọ pẹlu awọn ẹgbẹ rẹ, yio dara, ṣugbọn ṣọra ni gbogbo ojọ

**SAGITTARIUS** (Nov 23 - Dec 21) Ọgbọn ori rẹ yio mu ọ ṣẹgun gbogbo iṣoro ti o wa loju ọna rẹ, fi ẹsẹ rinlẹ gbọnin iwọ yio si duro daradare, Duro jẹ ki o si ṣe suru lati oni lọ.

**CAPRICOZN** (Dec 22 - Jna 21) Iwọ yio lo ọla rẹ ni aye kan ti o jẹ pe iwọ yio ni suru nigbati ijọngbọn ba de si ọ loni lairotẹlẹ.

OGUN GBOGBO NINU AWỌN OLORI DOKTA ELEGBOGI NI ILU JAMONU ṢẸṢẸ WA IDI RẸ KỌN TI NWỌN NPE NI:—

# 'UROLYSAN DRAGES'

Fun Itọ'u tabi fifọ Apo Ile Itọ (Kidney-Bladder) fun Ọkunrin ati Obinrin bi awọn amodi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu, ẹhin didun Ibadi Gige tabi riro, eri ile itọ, tabi itọ-jijo eniaitọ rirun, rukuruku Pipọn, sikileri itọ lati tọ to, lakuregbe, orunkun ọwọ, ẹsẹ, Ejika wiwu tabi riro



Ara sisan, titobiju aiko le gbe ara kọnkọn tabi kiakia didaji loru nigbakugba, ati orisirisi awọn aisan tabi amodi, ba wọn, yi ni egbogi ajẹbidan yi yio wo san lara rẹ ni kiakia ti alafia yio si de si ọ. Mej rẹko si ni ilu Naijiria nitorina ṣora ki awọn eleru tabi awọn ori rọbirọbi ma ta oriṣi emiran ti ko ni lari fun ọ, maṣe gba rara! Owo rẹ jẹ Sile mẹfa abọ 6/6d owo Oko Sile kan abọ (1/6d)

Bere Egbogi yi ni ṣọbu awọn:-

NIGERIA MEDICINE STORES
4, TINUBU STREET, LAGOS, PHNE 20278
Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Sitreet, Lagos.
Phone: 22878 Nigera, (Ọja Ita Faji)

# Awọn Ọja jẹbidan

Iwe ilana Ifa Iyanrin titẹ Etutu ṣiṣe iwosan ati egbogi jẹbeidan ti o ba ni iwe yi lọwọ, abiku ko ni yọọ lẹnu mi oso ati aje ko ni lagbara lori rẹ, owo paapa ko ni wọn ni ohunkohuni oba si dawọ rẹle ni yio ja si rere awọn baba awon ti o gbowo gba asọ lọwọ enia ko ni ri gba mi
Iye owo rẹ 20/-

Iwe egbogi ajẹbidan Agbabiẹtu awọn Ogun Ajẹbidan ti o wa ninu iwe yi ko ṣe sọ a fi ti o ba raa, ti o ba ni iwe wọwọ ṣaṣa warun ti o ko ni le wo ko si ri ijaya & yaran tabi mimu, ọ a si ka le pa o Iye owo 25/- a larin Ẹyọ Ajẹ ti o ba nfin turari yi ba a ti ṣe ṣuye rẹ Ajẹ ati abatenijẹ ko ni foju si ọ lara ohun kohun ti o ba si dawọle rere ni yio maa ja si, iwe ko mọ aita ọja agbana ko si ni wọ igba rẹ idabobo yio siwa fun iwọ ati awọn ẹbi rẹ.

| | |
|---|---|
| Pa golo kan | |
| Kekere | 10/6d |
| Iwe Gbedegbẹyọ Hausa | 2/6d |
| Itumọ Josẹfu Alala | 3/ |
| Itumọ Ami Ara | 5/- |
| Eewo ilẹ Yoruba ati Etutu | 3/- |
| Afọṣẹ Iṣẹdalẹ Yoruba ati Psalm Ajẹbidan | 4/6d |
| o ati agbara Psalm ẹgun lori awọn Ajẹ pẹlu Turari | 3/6 |
| | 30/- |

# APEJUWE ILE IṢẸ WA

Wọ Bọọsi ti o nlọ si Lawanson ni Yaba 3d pere ni, ti o ba sọkalẹ ni Lawanson, bere Ilu Itirẹ. Ti o ba de Ilu Itirẹ bere ibiti nwọn ti npa malu, titi ibẹ ti ile itawe wa wa Ti o ba fẹ fi owo ranṣẹ fun ọja ni ilerẹsi mi niyi:—
A ives Pa aki:- le ri awọn iwe wọn y ra ni gara dd, Mushin, Ikorodu road ati gbogbo ile itaja iwe Ti o ko ba ri i ra wa si ọdọ mi ngo ta fun.

J. O. Shoyinka
c/o Postal Agent,
1, Isiba Street
Itirẹ Via,
Suru Lere, Yaba

## Lati Oju Ewe keji



Oloye Ṣow mimọ

Ọkan ninu awọn agbẹjọro fun awọn ọdaran Dokita S. A. Aluko ọkan ninu oluko eto aje ni ilẹ ẹkọ giga julọ ti Unifasiti ti Ifẹ sọ pe Dokita Ọnabamiro ti wa ṣe iwadi lọwọ on nipa ero igbimọ Amoye eyiti ẹgbẹ Afẹni fẹre da silẹ. Awọn ẹlẹri to jẹri fun awọn ọdaran na jẹ enia merinlelọgbọn eyiti merindinlogun jẹ fun oloye Awolọwọ nikan.

Awọn ẹlẹri fun awọn Ọdaran na si bẹrẹ lati ma sọ ti ẹnu wọn ni ọjọ kẹrindinlọgbọn oṣu kẹrin ọdun 1963, Adajọ si sọ fun ile ẹjọ na pe o rẹ on diẹ ati pe ki nwọn da ile ẹjọ na duro fun igba diẹ.

Oloye Awolọwọ si bẹrẹ ọrọ lati fi ma ye ile ẹjọ nipa ẹsun ti nwọn fi kan ni ọjọ kọkandinlogun oṣu karun ọdun 1963 eyiti o fi ọjọ mẹsan pari rẹ Oloye Awolọwọ fi ye ile ẹjọ ninu ọrọ rẹ pe nipa gbogbo ọrọ ti Dokita Ọladipọ Maja ti fi han ninu ọrọ rẹ pe on lo gbero lati ditẹ si Ijọba Naijiria.

Amoye eyiti ẹgbẹ on da silẹ ati pe o si wa fun eto fun ilọsiwaju ẹgbẹ oselu ati pe on ko gba gbọ pe fun ti e o lati gbogun ti ilẹ Naijiria.

Agbẹjọro fun Ijọba bẹrẹ lati ma fesi si ọrọ ti Oloye Awolọwọ sọ ni ọjọ-kẹ-
WO OJU EWE KẸFA

## Itumọ Awọn Ami Ara

Ami meji ni o nbẹ lara, ọkandudu, ekeji pupa awọn meleji ni o si ni itumọ tirẹ lọtọ ọto.

Ami pupa ni odara julọ nitori ibikibi yowu ki o wa ni ara daradara ni enikẹni ti oba ni nitoripe Orire ko ni jina si oluwa rẹ.

### Itumọ Ami Ara

AMI ORI

Ẹnikẹni ti oba ni emi ni atari yio ṣiṣẹ papọ ,ere kinih ni yio si ma a jẹ iọjọ aiyee rẹ,, yio bi ọmọ pupọ, ṣugbọn diẹ ni yo ba a kale, Yio ni ẹmi gigun ati alafia lara

Etutu;- Ko gbọdo lo aṣọ alarabar a fi aṣọ funfun ,oru-uukchun ti ob si ri ṣe ni rere, ọjọ Abamẹta Satu-day ) ni ki o ma ṣe k oba le ni iyọrisi rere

AMI ETI ỌTU ATI OSI

Ẹnikẹni ti o ba ni nibẹ yio ni okiki ati ọla, ṣugbọn ko ni owo jaburata, ko si ni tawo na ni ọjọ aiye rẹ ọmọ diẹ ni Oluwa yio fi jiki rẹ, ṣugbọn wọn yio ni ẹmi gigun, aisan iwora yio ma ba ja nigbagbọ

IHO ETI

Iṣọra gidig di wa fun ẹnitio ba ni iru ami na na, nitori iku ojiji ỌmỌ- Pupọ ati ẹlẹmi gigan IṢẸ- Iṣẹ diẹ owo tabua pẹlu alafia ara ati ẹnu kukuru:

EWỌ

AṢỌ WIWỌ FUNFUN TABI KUBUSE

ỌJỌ OBA IRAWỌ RẸ MU- Tuseday ati Saturday ni ki o ma dawọle nkan rere ni ṣiṣe ki o ba le jasi rere.

AKIYESI

Si arakunrin arabinrin, Inu mi dun lati ṣe iwe yi fun kika gbogbo enia, iwe na si wulo ju wura ati fadaka lọ

Ewkẹni ti o ba tẹlẹ ẹyo inu iwe yi ko ni Kabawo Lailai Ifa yi rmu tilẹ ati etulu ṣiṣe wa nibẹpẹlu

Alafia fun nyin.

Emi
J. O. Shoyinka


# MODUPE PRINTING PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING

*Firms Patronise* MODUPE PRESS
*Becuase Of Their;—*

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHOD
PRINTING

*For Your Next Printing Jobs:—*
Just Call! 21985 - Leave the rest to Modupe

We Granantee Neat Work And Quick Service

**Modupẹ Printing Press**

**16, Bamgbose Street**
Phone 21985, Lagos.



# I. C. M. Tọniki (100 Tablets)




Gbiyanju lati ma lo I. C. M. TỌNIKI nigbagbogbo I, C, M, TỌNIKI o wa fun Ọkunrin, Obinrin ati Alabo yun pẹlu, I. C. M. Tọniki e dara fun aini ẹjẹ to lara, o nfun n i lagbara, o si ntun ẹjẹ ṣe daradara. Bere fun ẹyọ igo kan, tabi dosini. odidi Apoti ( 50 dozes ) wa pẹlu. Ilera ni ogun ọrọ o Bere lọwọ Elegbogi eyinbo ti o wa ni adugbo rẹ fun I. C. M. TỌNIKI (100 Tablets.)

Tabi ki o wa si ọdọ:—
MOSỌBALAJE MEDICINE STORES,
37, Palmchurch Street



GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TỌNIKI

ALE-BI-ELE Egbogi Tọniki Jamọnu titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan iṣẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo.

Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala lala ṣiṣẹṣẹ ti o kọ ie jẹun daradara, tabi ki o male sun dada ọkun lọsan tabi loru tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbo ki ṣe fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala ṣiṣe tabi fun awọn ailera gbogbo 'nyin ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja Ọgbọn ọdun o si de adọrin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ "DYNAMIREN' ni egbogi ti e nfẹ lati sọ ara di ọtun patapata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bi ẹ s'i dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugby'Arẹ" n'gbakugba yio salọ pẹlu igbaba-dun ati alafia diro de ọ. Iyẹn daju. Bere Egbogi na ni Ṣọbu: awọn

NIGERIAN- MEDICINE STORE
4, Tinubu Square Lagos

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

No. 749. TUESDAY JULY 21, 1964 (2D


## Isinku oloye Ada Ti Ilu Okeya Ko Ni GbaGbe

OKEYA:-Irohin ko to afojubu ni ojo oloye Adeyeye Ada ti iuu okeya fi saso kora ni ojo-kewa osu kefa odun yi oolopo omo ni ologbe Adeyeye fi sile nlau ninu awon omo ologbe na ni Alhaji Y. A. Bilesan .

Lesękeșe ti Baba na ti fi aye sile ni awon enia jankan-jankan ti bere si de si ilu okeya lati Irohin Offa oro, Ajasse-po Igbaja, Ilal, Oke ora ati awon ilumiran ti aye ko gba lati daruko wo n tan.

Ninu awon enia jankan-jankan to wa sibi eye isinku ologbe Adeyeye ni olola Alhaji Maijam Ya basa Irohin Alhaji Baba Oro Alhaji A. K. Abolare Alufa Abdulai Maijam Saidu Giwa Bale ati Alufa Moliki Sure-Lere,

Gbogbo awon enia Saraki-Saraki ni ilu okeya lo pese sibi isinku ologbe Adeyeye ninua won enia pataki ni ilu ologbe to pese sibi isinku na ni og' eni B. Ajilown, J. Essa Emiya, J. Elemosho M. Ibrahim Olorunloba, Oseni Kemofafe, Yahaya Yusufu, Karimu Balogun Amum Sarumoh ati J. Emulo Isale ore

Awon omo ologbe na ni si fi jije ati mimu te awon ebi ore to wa sibi eye isinku na.

# EGBE OSISE SO FUN AKINTOLA KI O FI IPO RE SILE

IBADAN:- Awon egbe osise Alakuko so ninu oro won ni Ibadan ni ojo isegun ti ise ojo kokand nlogun osu yi ki Olori egbe Demo ti nse Alakoso Ijoba ipinle Iwo Orun Naijiria ati Alakoso ijoba na Oloye S. L. Akintola Olori egbe Demo fi ipo re sile patapata.

Ninu oro awon omo egbe na to jade nibi ipade won ni na akowe egbe na Ogbeni Ogunlola Olawoyin Olanuyi fi ye Oniwe irohin wa pe oranyan ni ki Olori egbe Demo ati egbe na ti nse Akoso Ijoba Ipinle Iwo Orun fi ipo won sile patapata fun eto alafia ati ifaiya bale Ijoba rere ni ipinle na"

Ogbeni Ogunlola Olawoyin Olawuyi so pe ti awon egbe Demo ti nse Akoso Ijoba ipinle Iwo Orun Naijiria ba si leti fi ipo sile yio le je ki awon enia ipinle na le leti fun ara won lati mo Ijoba ti yio ba awon enia ipinle na lara mu ati pe awon enia ipinle na si nso de akoso Ijoba na eyiti egbe Demo (NNDP) nse ko si te won lorun ati fun ija eto nsele ni Ipinle na nigba gbogbo yi.

Awon egbe osise ti egbe Alakuko na tun fi ye oniwe irohin wa pe rogbodiyan nbe nbe sile larin awon omo ogbe Alakoso ni pinle Iwo orun Naijiria bayi awon omo egbe na ro olori egbe na ati Alakoso ipinle Ila orun Naijiria pe ki o tele dahun si oro na ati pe ki rogodinyan na na ba da okan miran sile larin awon omo egbe miran ani ni Ipinle Iwo Orun Naijiria

Awon omo egbe na tun fi ye oniwe irohin wa pe awon n dupe gidigidi lowo Olori egbe na ati Alakoso Ipinle Ila Orun Dokita M I



Oloye S I. Akintola
Alakoso Ijoba Ipinle Iwo—Orun

Okpara fun otitiyan re lori eto enia kika ti Odun 1963 ati pe awon omo egbe na si wa lehin re gidigidi fun gbogbo oro re lori eto enia kika ni ile Naijiria ti odun 1963

Nitori bati oniwe irohin wa fi oro na lenuwo lowo akowe egbe awon Osise egbe Alakuko pe nje Olori egbe won yio yio si na ja ija enia kika na lo gegebi Dokita Okpara ninu oro re ninu iwe irohin ni bi osu kan sehin? Akowe egbe na si dahun pe gegebi Olori egbe na ti so pe Ija lori enia kika na ko ti pari on otito ni Ogbeni Olawoyin so pe odigba ti awon ba ri otito eto enia kika na ki egbe won to duro.

## Ekunrere Idajo Oloye Awolowo (Apa 7)

Lati Oju Ewe Karun

ti osu kefa odun 1963, sugbon ni ojo kerin odun 1963 nwon da ile ejo na duro ni ojo kerin osu kefa odun fun ara okan nitori awon odara na ti ko di okan ninu won na ni Onitiri. Ile ejo na si duro fun



Ogbeni Latifu Jakande

odindi ose meta

Ile ejo na pari ni ojo ketadinlogbon osu kefa odun 1963 eyiti ile ejo fi osu mejo pari oro na

Ni ojo kokanla odun 1963 ni bi okan bi osu kan ati abo ti ile ejo na fi pari ejo na ni adajo ile ejo na si da ejo na eyiti o ni oloye Awolowo jebi esun na ti o si so awon enia metadinlogun pelu oloye Awolowo si ewon odun mewa titi de odun meji.

Adajo ile ejo na si tun da awon enia meta sile wa on ni ogbani J. S. Tarka ogbeni Victor Bisonab njo ati oloye Ekwejuor-Etche,

LATI OJU EWE KINI

egbe Afenifere lori ajumosepo laseko idibo si ile Igbimo asofin ti Apapo Ijoba Naijiria ?

Oniwe irohin so omo egbe na fi ye on pe ko ti to aseko ti nwon yio so iru oro be fun awon oniwe irohin ati pe eto si nlo lori ajumosepo egbe mejeji na bayi.


Printed and Published by Modupe Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street Lagos 21/7/64.